**Lakaye Ọrọ**

NIGBANA ni mo wo gbogbo iṣẹ Ọlọrun, pe enia ko le ridi iṣẹ ti a nṣe labẹ ọrun nitoripe bi enia tilẹ gbiyanju ati wadi rẹ, sibẹsibẹ ki yio le ri i, ati pẹlupẹlu bi ọlọgbọn enia rẹ lati wadi rẹ, sibẹ ki yio le ridi rẹ.

# Irohin Yoruba

NO. 834. May 31 — June 6, 1961 KOBO MEJI (2D)

**OWE**

Ina fi ikoko ṣawa, o ngba kurukuru s'omi. Abinuẹni ko ri koto tini si, ohun ti Ọlọrun yio ṣe ko fi han ẹnikẹni.

# AWỌN OLOYE AWOṢIKA ATI ṢOLARU BINU FI IPO-IṢẸ AMOJUTO WỌN SILẸ

**OKAN nia ti o ṣẹṣẹ ṣẹlẹ pe Ijọba Apapọ Naijiria yan awọn ikọ-iwadi kan lati wadi gbogbo iṣẹ ti o jẹmọ Ile-ifowopamọ ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ti a npe ni National Bank 'ti bi Ige, o si tun bi Adubi'.**

Nitori ti Ijọba Apapo Naijira ti bẹrẹ si gbogunti awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) nipa yiyọ wọn kuro ninu ipo amojuto iṣẹ LEDB ati bẹẹbẹẹlọ, ati nipa orişirişi iwadi awọn iṣẹ idagbasoke ilu t'o ba wa ni abẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre nṣe itọju rẹ, ni nwọn ba fi binu pe bi nwọn ko ba fẹ ọwọ awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ninu iṣẹ amojuto ti o ba jẹmọ ti Apapọ Ijọba Naijiria, awọn kuku yọ ọwọ awọn kuro nibẹ.

Oloye F. O. Awoṣika jẹ ọkan 'nu awọn alamojuto Igbimọ Banki Apapọ Ijọba Naijiria ti oruko rẹ wa ninu owo beba Naijiria ti a ngna nisisiyi. Oloye T. T. Ṣolaru paapa ti jẹ alaga Igbimọ Alamojuto Iṣẹ Oko Ofurufu Apapọ Ijọba Naijiria. Awọn Oloye mejeji binu fi iṣẹ na silẹ nitori iwọsi.

# ỌDUN ILEYA DUN L'EKO

LATI ọjọ aisun ọdun, ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu ti o kọja yi ni ilu orişirişi ti ndun yika origun mẹrẹrin Eko. Awọn ọmọ-ọlọdun l'ọkunrin l'obirin njẹ orişirişi onjẹ adidun ọpọlọpọ wọn si ngmu orişirişi ọti pẹlu. Nibẹ ni nwọn gbe fi igbadun ş'ayọ. Awọn Ẹgbẹ 'The House of Lords' ti Oloye T. S. Abiọdun Fujah si jẹ olori wọn lọ ṣe aisun ni ile olori wọn na. Nwọn jẹ nwọn si mu.

Ni ọjọ Ọjọbọ ti ṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu kanna, ọjọ keji ti nwọn ṣe aisun ọdun ijọ kọọkan ti mu awọn ijọ tirẹ josin fun Ọlọrun ni nwọn ba gbadura fun irẹpọ ati igbega ilu Eko. Nwọn dari lọ ile wọn pẹlu idunnu. Bi awọn orişirişi onilu ti nlu ni awọn kan nlajo mọra bi kokoro. Awọn kan si nfi kewu kọrin yin Ọlọrun logo titi



AWORAN yi ni ti awọn Musulumi ti o lọ jọsin ni Ọbalnde ninu Ọdun Ileya ti o kọja yi.

* * *

Ọpọlọpọ awọn ọmọ-ọlọdun na si nla ijo mọra bi kokoro. Orişirişi ẹgbẹ ni o lọ tẹtafo si ile baba-ẹgbẹ tabi alaga wọn.

Awọn Ẹgbẹ Kila Eko ti Ọgbẹni S. S. Shitta-Bey, ọmọ Oloye Seriki Musulumi Eko pe ṣọṣọ si ile baba-ẹgbẹ wọn, Oloye A. S. Agbabiaka. ni awọn Oloye Alhujaj, Alhaja, Alfa, gbajumọ Musulumi ati mẹkunnu Musulumi ṣe ẹṣọ ọkan-kọjọkan, nwọn si to lọwọlọwọ lọ si Mọṣalaṣi ọdun ni nkan agogo mẹjọ-abọ arọ. Omiran ninu wọn gun mọto-ayọkẹlẹ.

Ni nkan agogo mọkanla arọ lẹhinti awọn asiwaju ti nwọn fi de ile wọn.

Nigbati nwọn si de ile wọn olukuluku wọn si pa ẹran agbo rẹ, nwọn ha awọn ẹbi, aladugbo, ana ati ọrẹ wọn l'ẹran na, nwọn si se iyoku ni ọbẹ adidun ati ẹran-oniyọ. Ọdun na dun o larinrin. Irohin ko to afojuba ni. Aṣeyiṣamọdun o

# Ẹgbẹ Afẹnifẹre fi ẹjọ Benson sun Balewa

LAIPẸ yi ni Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) mu ẹsun kan lọ si ọdọ Alhadji Tafawa Balewa. Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria nitori apakan ninu awọn Minista rẹ ti o nda ipade awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre ru kakiri Ipinlẹ Iwọ-Orun lẹnulọlọyi lati da ijongbọn awuruju kan silẹ wipe rogbodiyan wa ni Ipinle na.

Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi, Igbimọ ti o ngbẹnuṣọ fun Ẹgbẹ Afẹnifẹre fi ẹjọ sun ninu ikede ti nwon ṣe l'Eko wipe: Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kokanlelogun oṣu yi ni awọn janduku kan ti o tẹle Ọgbẹni T. O. S. Benson, Minista Alamojuto Eto Irohin Ijọba Apapọ Naijiria wa da ipade Ẹgbẹ Afẹnifẹre ru nigbati Alhaji S. O. Gbadamọsi nsọrọ lọwọ ninu ipade ni gbangba ojude Itamito ni Ikorodu.

Gbogbo agbo ipade na toro, o si dakẹ rọrọ nigbati Alhaji Gbadamọsi mba awọn enia sọrọ iwuri ṣugbọn lojiji ni mọto Ọgbẹni Benson yọ sibẹ, bi mọto na si ti fun fere fa a ni awọn janduku ẹhin rẹ ba da ọpọoro okuta bo awọn ero inu ipade na. Lẹhin eyi ni Ọgbẹni Benson sọkalẹ ninu mọto na lati fi ara han awọn janduku ẹhin rẹ ki nwọn le tubọ mura si oko sisọ, o si la arin agbo ipade na kọja. Nṣe ni ipade na tuka, nwọn ko si le ṣe ipade na mọ ni ọjọ na.

# Tiwa-ntiwa National Bank tiwa ni

LATI igbati Ijọba Apapọ Ijọba Naijiria bẹrẹ ọran iwadi Ile Ifowopamọsi National Bank ti o ti di ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun nisisiyi ti bẹrẹ ni ọpọlọpọ awọn enia pataki-pataki kakiri awọn ilu Ipinlẹ Iwọ-Orun ti bẹrẹ si gba owo wọn kuro ninu awọn banki miran tabi ti awọn Oyinbo oniṣowo ti nwọn si nko wọn wa si "National Bank" bẹni awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ awọn ilu Ipinlẹ Iwọ-Orun paapa ti bẹrẹ si ko owo wọn wa si "National Bank". Awọn

(Wo oju ewe kejila)

# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

## Awọn Musulumi kan saara si Ijọba Iwọ Orun

AWỌN Musulumi Ila ti Ọrangun kọwe dupẹ lọwọ Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, Oloye S. L. Akintọla fun dida ti Ijọba da ọkan ninu wọn lọla lati lọ ṣe ẹsin ni Mẹkka ati Mẹdina lọdunni. Ẹniti Ijọba da lọla na li Alfa Anele Aminu Sheidu.

Ninu iwe idupẹ wọn awọn Musulumi na sọ pe inu Olori Imam, gbogbo Musulumi ati gbogbo ọmọ Ila tile-toko dun si ohun ti Ijọba ṣe fun ọkan ninu wọn ati fun ogo ilu wọn. Nwọn sọ pe, "Ni oruko Alah, awa faramọ iwọ ati Ijọba rẹ."

Nipari iwe wọn, nwọn gbadura pe "Iwaju ni ọpa ebiti yio ma a re si"—Ki Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, Oloye Akintọla ati gbogbo awọn Minista rẹ ma a lọ lati agbara de agbara ninu iṣẹ rere ti nwọn nṣe fun awọn enia Ipinlẹ Iwọ-Orun.

Bakanna, gbogbo awọn Musulumi ilu Ilaro ni Ẹgbado dupẹ lọwọ Oloye Akintọla fun atilẹhin ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ṣe fun Imamu ti ilu Ipake ni agbegbe Ilaro, Alfa Mummed Fadayiro lati lọ si Mẹkka ati Mẹdina.

Ninu Isin Akanṣe ti nwọn ṣe ni Mọṣalaṣi nla ti Ilaro laipẹyi, Alhaji Mustapha Adewunmi kansaara si Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun fun ifẹ ti o ni si ilọsiwaju awọn Musulumi ni Ipinlẹ Iwọ-Orun, o si gbadura pe ki Ọlọrun fi oreọfẹ ẹmi gigun ati agbara fun gbogbo awọn to nṣe Ijọba na, ki o si fi ibukun sori iṣẹ gbogbo ti nwọn ṣe fun alafia, ifọkanbalẹ ati idẹra awọn enia Ipinlẹ Iwọ-Orun ati ti Naijiria.

Ni ọdun yi, awọn Musulumi meje ni Ijọba Ipinlẹ wọ-Orun ranlọwọ lati lọ si Mẹka ati Mẹdina. Ki Ọlọrun ṣọ wọn pada wa sile ni alafia o.

## Iyaafin Adeoye bi ibẹta

ILARO.

LẸNULỌLỌYI ni obinrin kan ti orukọ rẹ njẹ Iyaafin B. Abikẹ Adeoye bi ibẹta ni ile-tọju awọn aboyun Ilaro, awọn ibẹta na si jẹ ọkunrin.

Nigbati irohin ti kan Ọba Alaiyeluwa Adekunle Ọjọbọ (Olu Ilaro) lara, ni o ti paṣẹ gẹgẹbi aṣa iṣẹdalẹ pe ki nwọn lọ lu gbẹdu" lati fi kede fun awọn ara ilu Ilaro pe obinrin kan bi ibẹta.

Iyawo Ọgbẹni John Adeoye ti iṣe olutọju ilekawe (librarian) Ado-Odo ni iya awọn ibẹta na, ati igbati o si ti bi wọn ni ọpọlọpọ awọn enia ti wa nyọ fun un.

## Williams bẹ ilu Ibẹju wo

OGBẸNI C. A. Williams Akọwe-agba Alamojuto Eto Ilẹ ati Ile Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun lọ bẹ ilu Ibẹju ni agbegbe Ẹpẹ wo lẹnulọlọyi, o fun awọn ara ilu na ni imọran lati tun ọna Okegun-Ọkọla ṣe dada ati lati sowọpọ ra mọto akero kan fun ilo wọn ati lati da iṣẹ ajumọṣepọ silẹ fun ilọsiwaju ilu wọn.

Ọgbẹni Williams ti pada si Ibadan.

## Ijọba Ibilẹ Oro jare

OGBẸNI I. O. Beckley, Adajọ agba Kotu Kekere Onireke Ibadan da awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ Oro (Oro District Council) lare nipa ẹjọ ti nwọn pe Ọgbẹni J. Adeyẹmi Olukọagba Ile Ẹkọ Giga (Christ High School) Ado-Ekiti fun ponun mẹtalelọdunrun o le ṣile mẹtadinlogun ati kọbọ meji (£303. 17s. 2d.) owo Ijọba Ibilẹ ti o wa ni abẹ itọju rẹ.

Nigbati o ni ye igba ti nwọn ti nbere owo na lọwọ rẹ ti ko si fi owo na silẹ, ni nwọn ba pe e lẹjọ. Adajọ si ni ki Ọgbẹni J. Adeyẹmi lọ -san ponun mọkanlelọgbọn ati ṣile mẹwa £31. 10s.) owo irinsẹ fun Igbimọ Ijọba Ibilẹ Oro (Oro District Council) ti iṣe Oludasilẹ Ile-ẹkọ gga 'Oro Grammar School'.


AGBAYANU
IROHIN ALAGBARA!
NWỌN NTA COMET
RADIO NI G.B.O.!
RADIO TO NLO
BATIRI TABI
TRANSISTỌ NI WỌN
OHUM WỌN
LAGBARA PUPO
NWỌNSI NSỌRỌ
KETEKETE ATIPE,
OWO PỌKU NI
NWỌN NTA WỌN




Awọn oṣiṣẹ-ẹrọ radio G.B.O. ṣe radio yi lati sọrọ dada nigbagbogbo
Aimọ to ba pọ o le fẹ ki nwọn o yẹ radio rẹ wo G.B.O. yio ṣe eyi fun ọ lowo pọku

Comet
RADIO SETS
G.B.O.
TECHNICAL DEPARTMENT

LATI GBO

G.B. OLLIVANT (NIGERIA) LTD.

# KADARA ẸDA (21)

ESIN igbagbọ ati ti Imale lodi pupọ si igbagbọ ninu egbogi, awure tabi isọra; awọn enia ti nwọn si gba-were-mọ ẹsin (religious fanatics) yio ma a sọ fun ọ pe, ko tilẹ tọna rara lati lọ eepisili (APC) tabi oogun Oyinbo miran bi ori ba nfọ ọ, tabi lati ri Dọkita rẹ, nigbati aarẹ ba e si o tabi si enia rẹ.

### IWỌ YIO BỌ KURO NINU IṢORO

Ṣugbọn dajudaju, a ri opọlọpọ ninu awọn Alufa ti o nwasu ni Ṣọọṣi,, ti babalawo kan ko si ni egbogi ju wọn lọ! Bakanna si ni ọpọlọpọ awọn asiwaju Imale miran ti ko ni iṣẹ meji ju "Iṣẹ Alfa" lọ. Bi o ba ni iṣoro kan ti o si mu u tọ wọn lọ, bi o ba si le san iyẹ owo ti nwọn ba yan fun ọ, dajudaju iwọ yio bọ kuro ninu iṣoro na.

Awọn enia si tilẹ nsọ fun mi pe, pupọ ninu awọn enia na a tilẹ ma a lo imọ ati agbara wọn si ọna odi lati ṣe buburu! Iru eyi mbẹ ninu imọ awọn enia funfun pẹlu, nwọn si npe e ni "apa osi". Lilo imọ ẹni ni "apa ọtun", ni pe ki a ṣe iwosan arun, ki a mu ọkan allera le, ki a ki enia laiya, ki a si s'agbara fun iranlọwọ eniti o wa ninu iṣoro ati bẹ ẹ bẹ ẹ lọ.

Lilo imọ ijinlẹ gba apa osi, ni k'a gbidanwo lati pa ẹnikẹni lara, lọnakọna nipa lilo egbogi tabi nipa agbara okunkun—agbara ajẹ tabi ti ogun ibi (Black Magic). Ki a ma si ṣe tan ara wa jẹ, agbara okunkun mbẹ nitootọ loju mejeji, ṣugbọn ki iṣe gbogbo enia ni o le ri gbese.

### NWỌN NI ADAHUNṢẸ TIWỌN

Pupọ-pupọ ninu awọn ọlọla, ọlọrọ ati olokiki enia ile aiye yi ni nwọn nbọwọ fun eewọ kan tabi omiran, ṣugbọn nwọn ko ni sọ fun o pe, bayi ni awọn nṣe. Ogunlọgọ wọn ni nwọn ni aworawọ, awo-atẹlẹwọ, elegbogi ati adahunṣe ni ikọkọ, ṣugbọn nwọn o ma a sọ ni gbangba pe, awọn ko gbagbọ ninu awọn nkan wọnyi.

O yẹ ki a ṣe alaye ṣeki nihinyi pe, igbagbọ ninu iru ohun kan ti a ba ri i pe o ṣeni ni anfani, ki iṣe iborișa rara, bẹni ki iṣe lati ka agbara Ọlọrun si asan. Nipa iru awọn nkan bayi, ohun ti o farapamọ ti a ko mọ l' o pọ pupọ ju eyi ti a mọ lọ. Iṣẹ Ọlọrun gbooro, oye awa ẹda ko si le ka a tan.

## Lati ọwọ M. A. Akinbọade, Ibadan)

### ỌLỌRUN NI O DA OHUNGBOGBO

Ọlọrun l'O da wa, On na l'O si da ohun gbogbo ti a ri ati eyiti a ko ri. On lo da ẹfọ tẹtẹ tabi odunduн. On na l'O si da eṣinṣin tabi eepin; On l'O da ewurẹ, On na l'O si da Kiniun. On l'O da mọnimọni (ekuku), On na l'O si da ipin ti o njo ni; On l'O da imọlẹ, On l'O si da okunkun! Bi a ba ronu lori eyi, a o ri i wipe awọn nkankan mbẹ ni aiye yi ti o yẹ fun ire ati alafia awa ẹda, nigbati awọn nkan miran mbẹ pẹlu ti o wa fun iparun ati ibi wa.

Nipa bayi, ki ẹnikẹni ki o maṣe ro wipe ipo ti on wa ni aiye yi ti ga ju ati fetisi ọrọ imọ ijinlẹ lọ, ẹnikẹni ko ga ju ofin Iṣẹda lọ rara. Lati ro iru ero yi ni lati ro wipe enia kan ti ga ju Ọlọrun ati awọn ofin ati Iṣẹ Rẹ lọ.

Mo mọ wipe awọn onijibiti mbẹ nipa ọna ẹkọ ijinlẹ nitootọ, ṣugọn mo fẹ ki o mọ pe otitọ ti o daju mbẹ pẹlu. Mo fẹ ki e ranti pẹlu pe kosi ibiti jibiti ati alupayida ko si ninu ohun gbogbo ti a nṣe ni aiye yi. A ti ka a ninu iwe irohin lọpọlọpọ igba, bi awọn enia ti lọ si orioko lati pe ara wọn ni ọlọpa tabi wolewole, tabi oṣiṣẹ ijọba oriṣiriṣi,, nwọn si ti ti ipa eyi gba owo nla-nla. Awọn ọlọpa Ijọba gan an ti mu awọn miran, ṣugbọn awọn miran mu iwa arufin na jẹ.

Nko ni ero rara lati tabuku tabi sọrọ odi si ẹsin k'ẹsin kan ṣugbọn o fẹrẹ dabi ẹnipe nitoripe ẹsin miran ti ilẹkun mọ ara rẹ ti ko si gba iru ẹkọ miran laaye lati wọle l'o njẹki awọn ẹkọ aṣiri wọnyi ma a dabi iborișa tabi ẹkọ eṣu loju wa. L'aiṣe aniani, koi ti pọju fun ẹda lati fi imọ diẹdiẹ ti a ba le ni nipa ẹkọ ijinlẹ kun eyiti Bibeli ati Kurani fi nkọ wa, niwọn igbati o jẹ pe gbogbo rẹ yio jijọ siṣẹ pọ fun ire wa ati ti awọn elomiran ni.

Ni nkan bi ọdun mẹta sẹhin a gbọ irohin kan lati ilẹ Kamẹrun ti o jẹ ara Naijiria nigbana pe awọn ara ilu kan ṣe kilọkilọ fun inginia (engineer) ti o nko awọn oṣiṣẹ ṣe ọna kan pe nwọn ko gbọdọ bẹ igi kan ti o wa laarin ọna na, afi bi nwọn ba le mu pọnun mẹwa wa ti awọn



M. A. AKINBỌADE

* * *

o fi ṣe etutu ki nwọn to bẹ ẹ. A gbọ wipe injinia na ke e mọ wọn lẹnu pe on ko gbagbọ ninu iru nkan bẹ. Ni kukuru, bi nwọn ti fi ọgbọn ati suru ge igi na to, nigbati o ṣubu lulẹ, o pa meji ninu awọn mẹrin ti nwọn gẹ e, o si pa awọn mejo yoku lara pupọ!

Ni ọdun 1952 ọkọ oju irin (reluwe) kan ṣubu ni Tẹṣan kan ti a npe ni Ilugun nitosi Ibadan, opolopọ ẹmi lo si run si ibẹ. Ni nkan bi ọdun kan lẹhin igbana ni ọrẹ mi kan ti o ti ngbe abule kan nibẹ sọ fun mi pe abule na ti tu patapata nitoripe niwọn opọlọpọ ọjọ ti iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ tan, lojojumọ ni agogo mẹta mẹta oru ni ariwo yio ma a bo awọn ara abule na mọlẹ. Nitoripe nkan agogo mẹta oru ni iṣẹlẹ na ṣẹlẹ nigbana, bo ba ti di agogo mẹta oru ni ariwo nla nla yio bẹrẹ, elomiran yio ma a ke wipe, "Ọwọ mi o, ori mi o, ah! ọmọ mi da, ati bẹẹ bẹẹ lọ. O sọ wipe afi igbati aba na tu ni igbadun to wa.

Iru awọn iṣẹlẹ wọnyi jẹ eyiti o ṣi ọna silẹ fun iwadi ati ẹkọ pataki ti o jẹ mọ igbesi aiye ẹda, ṣugbọn ẹnikẹni ko ya si iru rẹ.

Ẹ maṣe sọ wipe aroye mi pọ ju, mo fẹ ki nle ṣe alaye niwọn bi imọ temi paapa ti mo, ki ẹnyin paapa si le ri anfani lori diẹ ninu ohun ti mo ba sọ.

Ki a duro bayi na, Alafia fun nyin.

## Agbẹ ja agbẹ l'ole

ILỌRIN.

ADAJỌ Ilọrin kan sọ awọn agbẹ meji ti orukọ wọn njẹ Lawani Akani ati Dọja Arobadi s'ẹwọn oṣu meji-meji ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi nitoripe nwọn ji agbẹ ẹlẹgbẹ wọn ni iyere (locust beans) gbe ni Arobadi abule kan ni itosi Ilọrin.



# Ẹgbẹ Isọwọpọ awọn ẹlẹsin-iṣẹṣẹ ṣe ipade

EKO.

[illegible]

ITUMỌ ORUKỌ ỌRUN-MILA

[illegible]



Eyi ni aworan awọn ti Ẹgbẹ [illegible]



Olori ẹgbẹ [illegible] Ọlọrẹ Ajanaku, Araba Eko ni o joko larin yii

[illegible]






## Mọsilimọt s'oku baba rẹ

EKO.

[illegible]

## Muliki ku s'oja titi mọto

EKO.

[illegible]

## Ọpọ enia lu ẹniti nwọn ṣebi o ji ọmọ

EBUTE-METTA.

[illegible]

**Ẹ ma polowo ọja sinu iwe IROHIN YORUBA**



